# Alaye:
# "Awọn ipinlẹ mẹfa"

## Ti Sheikh Al-Islam:
## Muhammad ọmọ Abdul-Wahhab ọmọ Sulaiman Attamimi (ki Olọhun bawa kẹ)

Olukọwe ni:
Haitham ọmọ Muhammad Sarhan
Olukọni ni ile-ẹkọ Al-Haram ni Mossalassi Anabi - tẹlẹ - ati alamojuto ile-ẹkọ Sunnah

https://www.alsarhaan.com

Ki Olorun dariji, ati awọn obi rẹ, ati gbogbo eniti ti o ran lọwọ lati gbe iwe yii jade

Ontẹ alakọkọ

ẹtọ titẹ wa ni ipamọ

Ayafi ẹniti o fẹ tẹ tabi tumọ rẹ lati le pin lọfẹ lẹhin atunwo onkọwe naa

Jọwọ kan si:

islamtorrent@gmail.com

Ijọba ton seto iroyin

## ọrọ iṣaaju:

Ope ni fun Olohun, An yin logo, an wa iranlọwọ Rẹ, Asin wa aforijin Rẹ, An wa abo lowo Olohun nibi aburu ara wa ati nibi aburu isẹ wa, ẹniti Olohun bafi mọna, ko si ẹniti ole si lọna, ẹniti obaṣi lọna, kosi ẹniti ole fi mọna, Mo jẹri pe ko si ọlọrun kan ayafi Ọlọhun Allah nikan ṣoṣo, ti ko ni orogun, Mo si jẹri pe Muhammad ẹru olohun ni, ojiṣẹ Rẹ sini.

Ẹyin onigbagbọ, ẹ paya Ọlọhun gẹgẹ bi o ti yẹ ki a bẹru Rẹ, ẹma si ku afi ki eje Musulumi (Aal imran: 102) Eyin eniyan, e paya Oluwa yin, eniti Oda yin lati ara emi kan, O si seda iyawo re lati ara re, O sida lara won, opolopo okunrin ati obirin, epaya Olohun ti efin bere nkan ati okun ebi, Olohun nso yin o. (Anisaa: 1) Ẹyin onigbagbọ́, ẹ paya Ọlọhun, ẹ si sọ ọrọ oto, Olohun ose atunse isẹ yin, yoo si fori ẹṣẹ yin jin yin, ẹnikẹni toba tele Olohun ati Anabi, oni tohun ti jere (Al-ahzaab: 70-71)

lẹhin naa; Ohun ti o yẹ ki ọmọ akẹkọ mojuto ni mimọ awọn ofin ati ipinle ti Shariah gbe wa, ọkan ninu awọn tira pelebe ti o ṣe pataki, tio si nii ṣe pẹlu eyi ni tira Sheikh Al-Islam Muhammad ọmọ Abdul Wahhab ọmọ Sulaiman Attamimi, ki Olohun bawa ke, (oku ni 1206 hijrah), osọ tira naa ni (Awọn ipinlẹ mẹfa), Awon alfa se akole kan tira naa gan, oluko tira naa ṣe alaye awọn ipinle mẹfa ti Ọlọhun ati Ojisẹ Rẹ, fi idi rẹ mulẹ, tosi han daada.

Sibe naa, opolopo awon eniyan se asise ninu re, won si yapa si ohun ti Olohun se lofin, Awa se alaye tira yii ni ona tabili; kole di irorun lati mo, asi gbarale alaye Sheikh Muhammad omo Salih Al-Uthaymeen, (oku ni 1421 Hijrah), nibi alaye tiwa pẹlu afikun diẹ diẹ tani bukata si.

A n be Olohun ki O se ise yi ni mimo fun ohun nikan, ki o si se anfani fun onkowe ati eniti onkaa, ki ike ati ola Olohun ma ba ojise re ala fokan tan, ati awon ara ile re ati gbogbo awon saabe re lapapo, ati gbogbo enitin tele won pelu daada titi di ojo igbende, Openi fun Olohun, Oba gbogbo agbanla aye.

## Oro Isaaiu Iwe:

**Onkowe (ki Olohun bawa ke) sọ pé:**

Abere pelu Oruko Olohun, Oba Ajoke aye, Asake orun, Ninu awọn amin to tobi julọ, to tọka si agbara Ọlohun to lagbara julọ, ohun naa ni awon ipinle mẹ́fà tí Ọlọ́run se alaye re fun gbogbo eniyan, koja bi ase lero.

Lẹ́yìn èyí, ọ̀pọ̀lọpọ̀ ninu àwọn ologbon eniyan ṣe àṣìṣe nínú rẹ̀, ayafi awon díẹ̀.

Awọn ipinle mẹfa ni soki:

Ipinle akọkọ:
Ise mimo ati alaye idakeji re, tinse ẹbọ.

Ipinle eleekeji:
Ikojo ninu esin, ati kiko nibi ipin yeleyele.

Ipinle kẹta:
Gbigbọ ati itele aṣẹ awọn ijoba, idakeji rẹ jẹ iṣọtẹ ati aigbọran.

Ipinle kẹrin:
Alaye imọ ati awọn alfa, idakeji re nipe eniti o ba farawe wọn, ko si lara wọn

Ipinle karun:
Àlàyé nípa àwọn woni woli Ọlọ́run, idakeji re ni àwọn woli Sátánì.

Ipinle kẹfa:
Wiwa imọna lati inu Quran ati Sunnah, idakeji rẹ ni fifi Al-Qur’an ati Sunna silẹ

Kilode ti a fin ko awọn ipinle mefa?

[1] Nitori imọran awọn alfa lorire.

[2] Nitori ati ni imọ nipa awọn ipinle Islam, ini adiọkan wọn, ati isise pelu ẹ .

Olukowe bẹrẹ pẹlu bismalah, eyiti oje ọna ti gbogbo awọn alfa ngba bere, nitori pe:

[1] Ikose Quran ati awọn Anabi loje.

[2] Itele hadith: "Gbogbo ọrọ to pataki ..."; koda bojẹpe hadith yẹn lẹ

[3] Ikose àwọn Salaf, kí Ọlọ́hun kẹ wọn.

[4] Iwa alubarika pelu ibẹrẹ ni orukọ Ọlọrun

Itumo Bismillah?

[1] Mo bere sini ko pelu orúkọ Ọlọ́hun), lati fi orúkọ na wá alubarika.

[2] (Allah): Orukọ nla, ojẹ oruko Olohun ti gbogbo oruko n tẹle.

[3] (Oni ike): Ójẹ́ Oni ike to kari gbogbo ẹ̀dá.

[4] (Alanu): Eni ti O nfi aanu Re si eniti O ba fe ninu awon eru Re.

Njẹ erongba olukowe pẹlu ipinlẹ mẹfa nipe kosi imi mọ leyin e?

Ilana islam nipe ti won ba so onka kan ninu Quran tabi Sunna, tabi ọrọ awọn alfa:

[1] Ti ao bari onka to julọ ninu Quran ati sunnah, onka yi lama mulo, aani lekun, gẹgẹbi: awọn origun Islam ati awọn origun igbagbọ; bose wa ninu hadith Jibreel.

[2] Tia ba ri onka to julọ ninu Quran ati Sunna, onka yen koni agbọye niyen, Aa se afikun re pẹlu ohun towa latinu Quran ati Sunna, gẹgẹbi ọrọ Anabi: "Marun wa ninu adamo..." ati ọrọ rẹ: "ejina si awọn nkan iparun meje…".

Kilode ti wọn fin sọ onka nigbami ṣugbọn koni ni agbọye?

Eyi je ninu ẹkọ daada Anabi; Ó fẹ́ kí àwọn olùgbọ́ máa ha ohun tí oun mẹ́nu bà níbi ijoko ni, kí ó lè rọrùn láti ranti lẹ́yìn ìgbà díẹ̀; Gegebi oro re toso pe: "Nkan meta ni mo fi bura, mo si ba yin soro kan, ki e ha: Saara kii din owo eniyan ku …." Thirmizi lo gbawa, ohun sini onkowe tẹle.

awọn nkan pataki:

[1] Njẹ awọn salaf panupo lori awon ipinle mẹfa? beeni; Quran, Sunnah, oro awon sahabe ati salaf tọka si

[2] Tani akọkọ eni tokọ nipa awọn ipilẹ mẹfa? Ko si iwe igbagbọ tio soro nipa e, ṣugbọn ẹniti okọkọ kojo sinu iwe kan lọtọ ni imam mujaddid.

[3] Bawo ni aṣe le ha awọn ipilẹ mẹfa? Pelu mimo ipinle kọọkan ati idakeji rẹ.

Njẹ nkanaa ni awọn iwe “Ipinle Sunnah”, “Aqeedah”, “Sunnah”, ati iwe “Awọn ipilẹ mẹfa” koonu abi wọn yatọ?

Ojupono kanaa ni awọn iwe naa jee, ṣugbọn awọn alfa ṣe iyatọ laarin awọn akọle wọn ki oma ba su omo akeko, tabi fun alekun alaye, tabi bi ose ye kowa.

Nigba mi akọle iwe naa ajẹ "Awon ipinle Sunnah"; gẹgẹbi ti Imam Ahmad, tabi "Aqeedah" gegebi ti Sheikh al-Islam Ibn Taimiyyah, tabi "Sunnah" gegebi ti Al-Khalal, tabi "Igbagbo" gegebi ti Ibin Abi Shaybah, tabi "Tawheed" gegebi ti Ibin Khuzaymah, tabi "Awọn ipilẹ mẹfa" gẹgẹbi ti Imam Mujaddid.

# Ipinle akọko:

**Olukowe sọ pé:**

**Sise ẹsin fun Ọlọhun nikan ṣoṣo, kosi orogun fun, ati sise alaye idakeji rẹ tinse ẹbọ, atipe Al-Qur’ani se alaye rẹ daa, ti gbogbo eniyan ogboye.**

**Leyin naa, nigbati awon eniyan da bose da, esu so mimo di nkan mi mowon lowo, gegebi kan ma tabuku awon eni Olohun, osi so aworan ebo di ima nife awon eni rere ati titele won.**

Ise mimọ pelu Ọlọrun

(Ohun nipe ki eniyan gbero lati sunmo Olohun nibi ijosin re, kosi lewo inu ile aponle Al jannah), oko sinu:

[1]oláti jẹ́ onimimo sí Ọlọ́run nibi erongba rẹ̀.

[2]oláti jẹ́ onimimo sí Ọlọ́run nibi ife re

[3]oláti jẹ́ onimimo sí Ọlọ́run nibi gbigbe tobi.

[4] oláti jẹ́ onimimo sí Ọlọ́run ni kọkọ ati gbangba.

[5] Ki o jepe oju rere Ọlọhun ati Aljanah ile aponle lonfi ijọsin re wa.

Diẹ ninu ohun to soro nipa ise mimo ninu Al-Qur’an

[1]Sope irun mi, eran mi, emi mi, ati iku mi, ti Olohun ni, Oba gbogbo agbaye (anhaam: 162)

[2] Ao pawon lase jupe ki won josin fun Olohun pelu mimo (bayyina: 5)

(3) Ao ran anabi kan nise siwaju rẹ ayafi kia sofun pe kosi ọlọrun mi ayafi Emi, nitori naa ẹ jọsin fun Mi. (Anbiyaa: 25)

## Dię ninu ohun to soro nipa ise mimo ninu Sunnah

[1]Okunrin kan ni: bi Olohun ati ire bafe, Anabi wa sofun pe: “sofe somidi orogun Olohun ni? Kàkà bẹ́ẹ̀, sope bi Ọlọ́run nikan fẹ́.”

[2]Anabi ni: “Ẹnikẹni to ba bura pelu nkan toyato si Ọlọhun, oni tohun ti se ebo niyen.

[3]Anabi sope: “ẹyin eniyan; Esọ ọrọ, ema jeki Eṣu so yin nu, Emi ni Muhammad omo Abdullah, eru Ọlọhun ati Ojisẹ Rẹ, ema gbemi koja aye Olohun gbemisi.

## Idakeji isemimo ni ebo

[1]Olohun ni Ohun koni se aforijin fun elebo, sugbon Ohun maa n se aforijin fun ẹsẹ toba kere si ebo fun eni ti ohun ba fe. (Nisaa: 48)

[2]Olohun ni A ti ran ojiṣẹ si gbogbo ijo pe kiwon ma jọsin fun Ọlọhun, kan si jina si ebo (Nahl: 36)

[3] Anabi ni: “Enikẹni toba pade Olohun lai se ebo, yoo wo Aljanah, sugbon enikeni toba pade re pelu ebo, yoo wonu ina Jahannama.”

## Ebo pinsi ona meji

[1]Ebo nla tin yoni kuro ninu ẹsin:
Ohun ni: (gbogbo nkan ti Olohun bati pe lebo).
Fún àpẹrẹ: kí a ké pe ẹni tí ówa ninu sàréè, tàbí kí a pe ẹnití kò sí peluwa láti gbàwa.

[2]Ebo kekere tio le yoni kuro ninu ẹsin:
Ohun ni: (gbogbo isẹ tabi ọrọ ti Olohun se apejuwe rẹ bi ebo, sugbon ko tako Tawhiid).
Bi: ibura pelu nkan toyatọ si Ọlọhun, ati karimi.

## Ipele awọn eewo

[1]Ebo nla

[2]Ebo kekere

[3]Ese nla

[2]Ese kekere

## Iyatọ towa laarin ebo nla ati kekere

[1] Nnla:

- yio yoni kúrò nínú ìsìn.
- yio ba gbogbo awọn iṣe je.
- Eniti oba se yíò wo inú iná gbere.
- Eje ati owo oni tohun tidi eto lọdọ Oba.
- kio gbagbọ pe sababi nin dari agbaye.
- Olohun koni foriji toba ku sori e.
- Ki ẹri wa pe ebo nla ni.
- Kio gbagbọ pe eniti o yatọ si Ọlọhun lon dari agbaye.

[2] kekere:

- kole yoni kuro ninu esin.
- yio ba ise kan je.
- Eniti oba se koni wo inú iná gbere.
- ẹjẹ ati owo oni tohun kise eto.
- kosọ ohun ti Ọlọrun ko ṣe ni sababi di sababi.
- Iyapa enu wa lori aforiji rẹ to ba ku.
- Ki ẹri wa pe ebo kekere ni.
- gbogbo ohun ti o yori si ebo nla jẹ ebo kekere.
- Gbogbo nkan ti Sharia ba peni ebo tabi kufur ti ko si (al) niwaju e, ipinle nipe ebo kekere ni.

## Biberu ebo

Ebo farapamọ pupọ, Anabi ibrahim bẹru rẹ, gegebi Olohun se so fun wa ninu Alqur'an. Ibn Abi Mulaika sope: mo pade ogbon ninu awon saabe Anabi, gbogbo lon beru ise manafiki. Eni ti oba gbolohun gbo yio beru. Ao ma beru ebo pelu:

[1] Kikọ imọ Tawheed, iṣiṣe peluẹ, ipepe si idiẹ, ini suuru lori e.

[2] Kiko imo nipa ebo, ati mimo awon okunfa re; kale jina si.

[3] Adura ati wiwa iranlowo Olorun Oba.

[4] Yiyọ kuro ninu ebo ati awọn ẹlebo, ati jijinna si wọn; kí ó má baà dara wọn

## Ipinle keji

Olukowe sọpé:

Olohun pawalase pe ka sokan ninu esin, O si se ko fun wa pe kapin yelele.

Olohun se alaye re daada, ti gbogbo eniyan o gboye, osi ko fun wa pe kama pin yeleyele bi awon asiwaju ti won parun, osi sope ohun pa awon ojise lase pe ki won sokan ninu esin, konsi ma pin yeleyele.

Alaye re kun rere ninu Sunnah to mu iyanilẹnu wa.

ọrọ wa dipe pinpin nibi ipinle ẹsin ohun ni agboye esin, ipepe losi ibi isokan kosi eniti oun so ayafi kiwon peni were!

### Diẹ ninu ohun to soro nipa isokan ninu Al-quran

[1]Edi okun Olohun mu lapapo, ema pin yeleyele, esi ranti idera ti Olohun se fun yin, nigbati en barayin sota, Olohun si soyin di ore. (Alimraan: 103)

(2) Ẹ má dàbí àwọn tí wọ́n pín yeleyele, tí wọ́n sì pínyà lẹ́yìn tí àwọn ẹ̀rí tofojuhàn dé bá wọn, ìyà ńlá sì wà fún wọn (Alimraan: 105)

[3]awọn ti wọn pin ẹsin wọn, ti wọn si di ẹgbẹ, ẹyin ko si ninu wọn ninu ohunkohun. (anhaam: 159)

[4]Emáṣe fanfa, ki agbara yin maba lọ (anfaal: 46)

Dię ninu ohun to soro nipa isokan ninu Sunnah

[1] Mumini je omo iya mumini keji, ko gbo se abosi fun, ko gbodo yeye e, igbaya ni ipaya Olohun wa, Anobi fi owo si igbaya, Eewoni fun musulumi ko pa musulumi egbe e tabi kobu tabi ko gba owo e.

[2] Eye se keeta ara yin, eye korira ara yin, eye fura si ra yin, eje omo iya nini esin

[3] Mumini si mumini da gegebi ile nio, ti apa kan di apa kan mu.

Ní ìyàtọ̀ sí èyí, Ànábì, kọ gbogbo ohun tí ó lefa ki àwọn mùsùlùmí pínyà, ó sì ni ki a ṣọ̀kan ki a si nìfẹ́ ara wa.

Iṣẹ awọn Saabe

Àríyànjiyàn wà láàárín wọn, ṣùgbọ́n kò yọrí sí ìyapa, tabi ìṣọ̀tá, tàbí ìkórìíra. Ninu apẹẹrẹ iyapa wọn ni asiko Anabi nigba ti o so leyin ogun Ahzab: “Ẹnikan ninu yin ko gbodo kirun ayafi ni ile awon Quraiza” Nigbati won paya ki asiko ma lo, Awom kan sope: Atigbo asi tele, Awon miran sope: ama kirun lasi ko e nitoripe Anabi kan fe kia yara ni, won osi bu ra won.

Ise awon Salaf

Ọkan ninu awọn ipinle Ahl al-Sunnah nibi awọn ọrọ ariyanjiyan ni pe, ti ariyanjiyan ba da lori igbiyanju, o si jẹ. Àwọn apakan nínú wọn mangba awawi ara won wole, wọn si kìn se keta ara wọn.

Lara awọn apeere isokan ninu Sharia Islam

| | | | | |
|---|---|---|---|---|
| Khalipha je okan | Ibudojuk o wa jẹ ọkan | A n ṣiṣẹ pelu ofin sharia kan | À ń tẹ̀lé anabi kan | A pejọ lati sin Ọlọrun kan |
| Gbogbo eniyan pade ni ojo Arafah | A n pade ni gbogbo Eid al-Fitir, tofi mo awọn obinrin ati awọn ọmọde laisi idapọ | Gbogbo ara ilu n pade ni gbogbo ọjọ Jimọ | A máa ń pàdé ládùúgbò kọ̀ọ̀kan lẹ́ẹ̀merùn fún irun tó jẹ́ dandan | |

akiyesi:

Hadeeth "Iyapa awon ijo mi ike ni" kole jẹ eri. Tori ti iyapa baje ike, kiwa ni isokan ma je?!

# Ipinle keta:

**Onkowe sope:**

**Ninu pipe isokan ohun nipe kia gboro kia si tele ase asiwaju wa, koda bío jẹ́ pé ẹrú Abisinia ni.**

**Ọlọ́run se alaye re daada, ni oríṣiríṣi ọ̀na ninu sharia ati kadara. Sibe naa** ọpọlọpọ awọn ti wọn pera won ni alfa, won ko mo, bawo waani won se fe sise pelu e.

Gbigbọ ati itele asiwaju yio jẹ:

[1]pelu sise oun toba palaṣẹ

[2] pelu fifi ohun tokọ silẹ.

Diẹ ninu awọn ohun to soro nipa oranyan titele asiwaju ninu Quran

(1) Mope Ẹ̀yin tí ẹ nigbàgbọ́, ẹtele Allāhu,ẹ sì tele Òjíṣẹ́ àti àwọn aláṣẹ ínú yín. Nisa: 59

(2) Etele Allāhu àti Òjíṣẹ́ Rẹ̀, ẹ máṣe fanfa, bí bẹ́ẹ̀ kọ, agbára yín o sì lọ. Anfal: 46

[3] ẹdi okùn Ọlọrun mu ṣinṣin, ẹ máṣe pinya. Alimran: 130

Diẹ ninu awọn ohun to soro nipa oranyan titele asiwaju ninu Sunna:

[1] Afi owo luwo pelu Anabi lati se adehun pe aagbo asi tele ase re, ni gbogbo igba, aa sini bawon alase se fanfa, ayafi ki a ripe ose keferi tofoju han pelu eri.

[2]. Enikeni toba ri nkankan lodo asiwaju re kose suuru, nitori pe eni to ba yapa jamah to wa ku, iku jahiliya loku.

[3] “Ẹniti o ba yọwọ kuro ninu itele ase, yoo pade Ọlọhun laisi awijare fun.

Ẹnití óbá wo itan isesi ijo musulumi yio ripé:

[1] Nígbàtí won wàní ìṣọ̀kan, tí won si bọ̀wọ̀ fún àwọn awon alase, tan sìn tẹrí ba fún wọn, Awon ni won je asiwaju lórí ilẹ̀.

[2]Nigbati ohun toṣele si sele, tiwọn pinya, tiwọn ṣọtẹ si asiwaju wọn, Ìbẹ̀rù won kúrò lọ́kàn àwọn ọ̀tá wọn, agbára wọn sì lọ, àwọn ijo miran bori wọn, wọ́nwa dabi fukufuu ori odò.

Nnkan toje oranyan funwa ati asiwaju ati omoleyin

Ki a se ohun ti Olohun palase fun wa ni ife ati ifowosowopo lori daada ati ipaya Olohun, ati pe kia kojo lori ododo, ki a si fowosowopo lori re, kia si se mimo nibi gbogbo ise wa, kia si gbiyanju lati tun ijo wa ṣe bia se lagbara mo, ko si le ṣee ṣe, ayafi tia ba fi ariyanjiyan ati fanfa silẹ laarin wa.

## Ipinle kẹrin:

Onkowe sope:

Alaye ìmọ̀ àti àwọn onimimo, Ati alaye pe, eniti oba farawe wọn kii ṣe ara wọn.

Olohun ti se alaye ipinle yi ni ibere suratu bakora lati to sope: eyin omo isreli eranti idera mi ti mose fun yin. (Aya: 40) titide ibi oro Olohun kio to soro Ibrahim: eyin omo isreli. (Aya: 122)

Alaye naa han kedere ninu Sunnah fun gbobgo eniyan, tio ko ọ̀pọ̀lọpọ̀ ọ̀rọ̀ sinu.

Lẹhinna eyi wa eemo julọ, debipe imo wadi adadale ati anu, ohun ti won se nipe: won da otito po mo iro! ìmọ̀ tí Ọlọ́run fi lélẹ̀, kosi eniti onso ayafi ki wonpe ni aṣiwèrè, Ẹnikẹ́ni tó bá sì tako imo naa, ohun ni won peni onímimọ̀!!

Imọ pinsi ona meji:

[1] Imọ Sharia ati ohun ti o jọmọ: (ìmọ̀ ohun tí Ọlọ́hun sọ̀kalẹ̀ sí Anabi Rẹ̀ nínú àwọn ẹ̀rí àti ìmọ̀nà). Ohun ni oni oriyin, ohun si ni ipilẹṣẹ ninu Quran ati Sunnah.

[2] Imọ ti aye: Bii imọ medicine, ati engineer, ati awọn miiran, ope orisi risi :

[A] Ti o ba jẹpe ọna daada ni; ohun naa daa niyen.

[b]Tio ba jẹpe ọna aburu ni; aburu ni ohun naa niyen.

[C]Tio baje kosi ni nkankan ninu mejeji, ifi akoko sofo niyen o.

Dię ninu ohun to wa ninu eyin fun mimọ:

[1] Olohun ni: Sọpe: Nję awọn toni mimọ ati awọn ti koni mọ dọgba? Awọn toni ilaakaye nikan ni o ranti. (zumar: 9)

[2]Anabi ni: "Àwọn anabi olohun kò fi owo kale komaje ogun bikose imo, eniti oba mu imo naa, oti jere topo.

[3] Anabi ni: "Ẹnikẹni ti Ọlọhun ba fẹ oore fun, Yio fun ni agboye ẹsin."

Ninu awọn ola tonbe fun mimo:

[1]Olohun o gbe oni mimo ga ni aye lodiwon bio tifi sise se, ati ni ojo ikeyin ninu Aljannah.

[2] Imo je ikan ninu awon ohun tio seku fun eniyan lẹhin iku rẹ, Nitori teyan baku, yio seku nkan meta, ninue ni imo wa.

[3] keeta leto nitori ẹ: "Ko si keeta ayafi ninu nkan meji: ọkunrin ti Ọlọrun fun ni owo, ati ọkunrin ti Olorun fun ni oye osi fin dajo ati osin ko awon eniyan.

[4] Ogún Anabi ni, "nitori ogun imo ni Wọn fi kale".

[5]Imọlẹ ni ti nmọlẹ fun eru; Nítorí náà, ó mọ bí ó ṣe lè jọ́sìn Olúwa rẹ, àti bí ó ṣe ń ṣe sí àwọn ẹlòmíràn.

[6] Ayé jẹ́ ìmọ́lẹ̀ tí ń tọ́ àwọn ènìyàn sọ́nà nínú ọ̀rọ̀ ẹ̀sìn àti ti ayé.

Nnkan toje ọranyan fun wa:

A gbodo lomo awon ti won je onimimo looto, awon ni Alfa Olohun ti won to awon eniyan ni ona sharia, ninu awon ami idanimo won ni: Quran ati Sunna loman fi se eri, oju ona awon salaf ni won man to, ijosin fun olohun ni gbogbo gba, won man ko fun awon eniyan kuro ni ebo ati adaadale.

## Ipinle Karun:

Olukowe sope:

Alaye ti Olohun se nipa awon woli, ati opinya tose laarin won ati awon ti won sebi won ti won manafiki ota Olohun.

Aya inu surat Al-imraan tito lati se alaye, ti Olohun sope: Sọfun wan pé, tí ẹ bá nife Ọlọ́run, ẹtẹ̀lémi, Ọlọ́run yóò sì nife yín. (Aya: 31)

Ati aya towa ninu surat maaida ti Olohun sope: Ẹ̀yin ẹni tíe gbà Olohun gbọ́, ẹnikẹ́ni tóbá yí padà kúrò nínú ẹ̀sìn rẹ̀, Allāhu yóò mú àwọn ènìyàn miran wa tí yóò nife wọn, awon naa yóò nife Rẹ̀. (Aya: 54)

Ati aya towa ninu surat yunus ti Olohun sope: Dájúdájú àwọn woli Allāhu kònı́ ìbẹ̀rù, bẹ́ẹ̀ni wọn kò ní bànújẹ́. Àwọn tí wọ́n gbà Olohun gbọ́, tí wọ́n sì paya Ọlọ́run

Nigbana ọrọ naa wa da lodo awon tin perawon ni onimimọ ati oni sharia, woni woli gbodo fi itele Anobi kale, ogbodo fi jihad sile, ogbodo fi igbagbo ati ipaya Olohun sile, enikeni toba se awon nkan wonyi kosi ninu won.

Olohun dakun se amokuro fun wa o, Iwo ni oba ton gbo adura.

**Bawo ni aṣefe da woli Ọlọrun mo?**

| | |
|---|---|
| Awọn ni eniti ogba Ọlọhun gbọ, ti wọn bẹru ẹ, ti wọn si duro deede ninu ẹsin. Olohun sope: Dájúdájú àwọn woli Allāhu kònı́ ìbẹ̀rù, bẹ́ẹ̀ni wọn kò ní bànújẹ́. Àwọn tí wọ́n gbà Olohun gbọ́, tí wọ́n sì paya Ọlọ́run. (Yunus) | Ki eniyan ma pera ẹ ni woli, onfo raẹ mo niyen, èyí sì lòdì sí ipaya Ọlọ́run. Olohun sope: eye forayin mo, Ohun lomo eni to paya ohun. (Anajm) |

Onkowe so aya mẹta:

[1] Sọfun wan pé, tí ẹ bá nife Ọlọ́run, ẹtẹ̀lémi, Ọlọ́run yóò sì nife yín (Al-imraan: 31)
Eyi ni a n pe ni aya iadanwo, Al-Hassan Al-Basri sọpe: Ni asiko Anabi, awọn kan maa n sọpe: Awa nife Olohun gan, Olohun wafe fun ife re ni ami, owa so ayayi kale

[2] Ẹ̀yin onigbàgbọ́ ododo, ẹnikẹ́ni tóbá yí padà kúrò nínú ẹ̀sìn rẹ, Allāhu yóò mú àwọn ènìyàn miran wa tí yóò nife wọn, awon naa yóò nife Rẹ̀ ([Al-Ma'idah: 54]. Olohun royin won pe:
(1) Won rera won le fun awon mumini.
[2] Won lagbara lori awon keferi.
[3]Wọn jagun lati gbe esin Ọlọhun ga.
[4] Wọn kin bẹru eebu enikan nibi esin Ọlọhun.

3 Dájúdájú àwọn woli Allāhu kòní ìbẹ̀rù, bẹ́ẹ̀ni wọn kò ní bànújẹ́. Àwọn tí wọ́n gbà Olohun gbọ́, tí wọ́n sì paya Ọlọ́run (yunus: 62,63)
Osalaye pé àwọn woli rẹ̀ ni onigbàgbọ́ nínú ọkàn tosi paya e.

Sheikh Islam Ibin Taimiyyah sọ pe:

Olohun salaye ninu tira re ati Sunna Anobi Re, pe Ohun ni awon woli ninu awon eniyan, Sàtánì naa ni woli, nitori naa iyato wa laarin awon ore Olohun ati awon ore Sàtánì:

[1] Awon woli Olohun:
Olohun so bayi nipa won: Dájúdájú àwọn woli Allāhu kòní ìbẹ̀rù, bẹ́ẹ̀ni wọn kò ní bànújẹ́. Àwọn tí wọ́n gbà Olohun gbọ́, tí wọ́n sì paya Ọlọ́run. (Yunus)

[2] Awon woli esu:
Olohun so bayi nipa won: dajudaju agbara esu yoo ma be lori awon ore re ati awon elebo (Anahl)

Sheikh Islam Ibin Taimiyyah sọpe:

Awọn alfa sọpe: (Ti ẹ ba ri eyakan tonfo ninu afẹfẹ, tonrin lori omi, emaṣe jẹ ki o tan yin jẹ titi ti eo fi rii pe o duro nibi awọn aṣẹ ati awọn eewọ).

Awọn woli Ọlọrun wa ni ipele meji:

[1] Awọn ti won ṣaaju.

[2] Awọn ara apa ọtun

Olohun daruko won ni opolopo aaye ninu Alquran: ni ibere ati opin Surat Al-Waqi'ah, ninu Al-Insan, Al-Mutaffifeen, ati ninu Surat Al-Fatir.
Aljannah sì jura wonlo púpọ̀, àwọn woli Olohun tan ni ígbàgbọ́ tan si paya Ọlọ́hun won o wani inu Aljannah bi ìgbàgbọ́ àti ipaya Olohun wọn base to.

ọna ti awọn eniyan pinsi pelu awon woli Olohun:

[1] Alaseju: Ẹnikẹ́ni tóbá gba pé woli Ọlọ́hun ni eyakan: yi o gbàfun nibi gbogbo ohun toban sọ nípa Olúwa rẹ̀, ati gbogbo ohun toba ń ṣe.

[2] Alaseku: Ẹnikẹ́ni tóbá rípé óń sọ tàbí on ṣe nkan to yapa Sharia: oti kúrò nínú ije woli Ọlọ́run yanyan, kódà bóbá jẹ́ oni igbiyanju to se àṣìṣe.

[3] Oni wantu wosi: Ẹnikẹ́ni tíki se alai dese tàbí ẹlẹ́ṣẹ̀ tóbá jẹ́ oni igbiyanju to se àṣìṣe, kò gbọ́dọ̀ tẹ̀lé nibi gbogbo ohun tóba sọ, kò sì gbọ́dọ̀ pe ni keferi àbi poki pelu igbiyanju rẹ̀.

Karaamo awọn woli Olohun

[1]To fese rinle: Wọn ni karaamo ti Ọlọhun fi pon awọn woli Rẹle, ati pe esa awọn Woli Ọlọhun ni karaamo wọn nitori eri ninu ẹsin, tabi bukata awom Musulumi.

[2]Aamin ni fun Anobi: Oun nipe karamo yi ṣẹlẹ pẹlu alubarika itele Anobi ni, nitorina ninu awọn amin Anabi naa lowa.

[3] Ko pidan dan fun woli: Karaamo lejẹ gẹgẹ bi bukata eniyan, ati pe ti o ba nilo karamo nitori igbagbọ rẹ tole, yio ri karaamo tio fun igbagbọ rẹ lagbara, eniti koba nilo koni ri, nitori idi eyi owa laarin awon Taabihi ju awon sahabe lo.

Awon nkan to dasha lu

O jẹ: (ohun ti o wa ni ilodi si ohun ti awọn eniyan ba saaba, gẹgẹbi fifọ ninu afẹfẹ, tabi rin lori omi), opinsi ona mẹrin:

[1] Amin: Tawọn anobi Olohun ni, aani peni mujisa, Nitoripe eleyi ni ohun to wa ninu Al-Qur'an, ati pe mujisa, awọn kan lema lagbara e, kosi jẹpe kii ṣe ti Anabi, sugbon kosi ẹnikan tole ni ohun ni amin lẹyin iku Anabi Muhammad.

[2] Karaamo: Yoo jẹ ti awọn woli Olohun, awọn ni wọn ni igbagbọ ati ipaya Olohun, apejuwe karaamo ni ohun to ṣẹlẹ si awọn ashab kahf

[3] Mujisa tabi fitina: Tawon woli Satani ni, ao maa mọ latara mimo isesi nipa ẹni naa, koni ni igbagbọ ati iberu Olohun, apejuwe re ni ohun ti o ṣẹlẹ lati ọwọ Dajjal.

[4] Yeye: Ẹnikẹ́ni tó bá parọ́ mọ́ Ọlọ́hun, ọlọ́hun o yeye e ni ayé síwájú Alqiyamah, apejuwe re ni eyi to ṣẹlẹ̀ sí Musailamah òpùrọ́, ofẹ atejun si oju alaisan, oju bafọ.

ẹka awọn eniyan nibi awọn nkan to daṣalu:

[1]Enitio gbagbo: Oni kosi fun àwọn to yato si awon Ànábì Olohun, ósese ko gbàgbọ́ lápapọ̀, yio si pe ohun tí won sofún nípa ọ̀pọ̀lọpọ̀ ènìyàn niro nítorí

[2] Alaseju: Ólerò pé gbogbo eniti óbá ti sen kan to daṣalu otidi woli Ọlọrun.

[3]Wantunwosi: Ó gbàgbọ́ pé Ọlọ́run máa ń fún ẹnikẹ́ni tí ó bá fẹ́ ninu awon eru Rẹ̀ ní iṣẹ́ to dasalu, ṣùgbọ́n kì í ṣe gbogbo nkan to dasalu ni karaamo, biko sewipe, ole wáyé lọ́wọ́ onidan àti ẹlẹ́tàn.

ìyàtọ̀ tówà láàrin àwọn woli Ọlọ́hun àti àwọn woli Sàtánì láti inú ìwé "Al-furqan" ti Sheikh Al-Islam Ibn Taimiyyah

| Awọn woli Ọlọrun | Awọn woli Satani |
| --- | --- |
| – Wọn tẹle Quran ati Sunnah. | – Wọn yapa Quran ati Sunna. |
| – Wọni igbagbọ ati ipaya Olohun (awọn eniyan jẹ ohun alumọni, olu paya Olohun loni ola julo). | – Awọ́n iroyin keferi, ìwà pálapàla, idán, wèrè, lowa lara won. |
| – Wọn tẹle Anabi, wọn kin yapa Sharia rẹ. | – Wọn tako Anabi, wọsin yapa Sharia rẹ. |
| – Wọn rọ awọn eniyan lati: tẹle Anabi, ṣe iṣẹ ọranyan, ati gbigba dura. | – Wọ́n rọ àwọn ènìyàn láti tẹ̀lé wọn, bẹ́ẹ̀ ni wọn kìí ṣe àwọn ojúṣe tójẹ́ oranyan, wọn sì kin se Adua. |
| – Wọ́n gbàgbọ́ pé Ànábì lola ju Woli lọ, àti pé Woli kìí ṣe eni aso nibi àṣìṣe. | – Wọn gbagbọ pe Woli ni ola ju Anabi lọ, kosi kin se asise. |
| – Igbagbo ati ipaya Olohun ni okunfa karaamọ (ẹsan ati iru iṣẹ man jo rawon). | – Mujisa tabi fitina tabi yeye lowa fun wọn, kosi rorun ki keferi je woli, wọnsi man yin awọn keferi. |

### Awọn woli Ọlọrun:

- Oye kia feran won nitori Olohun.
- Wọn man bẹru sobeselu, wọn kin gba etanjẹ nibi isesiwọn.
- Wọn kin yara wọn soto, Sunna si man han lara wọn.
- Wọn kin se aseju tabi abuku.
- Wọ́n jẹ́ onigbàgbọ́, ní koko ati gbangba.
- Enikeni toba so wipe Muhammad, imo gbangba nikan lo mo, komo imo koko; keferi ni oni tohun!
- Kosi iru Anabi Muhammad.
- Wọn fi kadara jeri si awon adanwo nikan, kii ṣe lori awọn aṣiṣe.
- Wọn kin taku sori ẹṣẹ, eyi jẹ ọkan ninu awọn ami ifẹ Ọlọrun si eru ẹ.
- Mosalasi ni aye ijọsin wọn.
- Karaama tóga jùlọ lodo wọn ohun ni ki eyan se deede.

### Awọn woli Satani:

- Oye Kia korira won nitori Olohun.
- Wọn kin bẹru sobeselu, wọn si man gba etanjẹ nibi isesiwọn.
- Won man yara won soto pelu aso, irun ati awon nkan miran, won sebi awon keferi.
- Wọn ni aseju ati abuku.
- Wọn ṣe iyatọ laarin igbagbọ koko ati gbangba.
- Awọn ọmọlẹhin wọn gbagbọ pe wọn mọ koko.
- Awọn ọmọlẹhin wọn gbagbọ pe ikan naa ni woli ati anabi.
- Kadariyyun niwon lakoko itele ase, Jabriyyun niwon lakoko ese.
- Wọn gbagbọ ninu ije okan soso bibe Olohun ati eniyan.
- Satani nin yo si wọn; Wọ́n rò pé Malaika niwọ́n.
- Awọn ọmọlẹhin wọn gbagbọ pe iroyin anabi ati malaika nbe lara won.
- Wọ́ so saare di mọ́sálásí.
- Wọnṣe ohun tio mu isesi Satani lagbara gegebi: gbigbọ orin, susufe, ati pipa at ẹ wọ

# Ipinlẹ kẹfa:

Onkowe sọpé:

Dida iruju ti Sàtánì daale pada, nibi fifi Qur'an ati Sunnah silẹ, ati titẹle awọn ifẹ inu orişirişi; ohun nipe kosi eniti omọ Qur'an ati Sunna ayafi mujtahid; Mujtahid sini eniti oni awon iroyin tosepe ale mari ni pipe lara Abu Bakr ati Umar!

Ti eniyan ko ba ri bayi, koya yago fun, ko si iyemeji nipa re. Ẹnikẹ́ni tóbá wá ìtọ́sọ́nà lọ́dọ̀ wọn, poki tàbí wèrè ni nítorí isoro towa nibi agboye won!! Mimo fun Olohun, opolopo igba ni Olohun se alaye bi asele da iruju tiodayi pada, debipe otidi kose mamo: (Sugbon opolopo eniyan ko mọ) (Alaraaf: 187) (Dájúdájú ọ̀rọ̀ náà jẹ́ òtítọ́ sí ọ̀pọ̀lọpọ̀ wọn, nítorí náà wọn kò gbàgbọ́, Àti pé, A ti fi ẹ̀wọ̀n si wọ́n lọrùn, titidé agbọ̀n won. Atifi gaga si waju ati eyin won, asi bo won daru, won ko riran. Booba se ileri fun won tabi oose ileri fun won, won kole gbae gbo. kìlọ̀ fún ẹni tó tẹ̀lé Quran, tósì paya Olohun ní koko, fún ní iro idun nu pe Olohun yoo foríjìn yoo si san ni ẹ̀san rere. (yaasin).

Igbiyanju:

[1] Ẹ̀dè:
Igbiyanju lati mọ nkan to le.

[2] Lilo:
Igbiyanju lati mọ idajọ ofin Sharia.

Ninu awọn majemu igbiyanju

[1]kolo mọ iyi toni bukaata si fun igbiyanju re ninu awon ẹri sharia gegebi awon aayat ati hadisi idajo.

[2]kolo mọ nipa ilalafia ati lile hadisi; gẹgẹbi isnaadi ati awọn to gba hadisi wa.

[3]kolo mọ awọn aaya toti parẹ ati awọn aye ipanupo awon Alfa, kio maba fi Aayat toti pare ṣe idajo.

[4]kolo mọ awon ẹri ti idajọ re yato; kio ma ba dajo pelu nkan to lodi si iyẹn.

[5]kolo mọ nipa ede larubawa ati furua daada, kole ma dajo pelu itunmo awon gbolohun ede yii.

[6]ko ni agbara lati yo idajọ jade ninu awon ẹri wọn.

Nje igbiyanju man pin?

Bẹẹni, igbiyanju man pin, o si mawa ninu ojupona ọkan ninu awọn ojupona imọ.

Mujtahid gbodo se igbiyanju, lehin na:

[1]Ti idajọ ba han si, yo se idajo pelu e, sugbon:

[A]Ti oba so aso bade yoo gba esan meji: ẹsan fun igbiyanju rẹ, ati ẹsan fun asobade re, nitori fifi ododo han wa ninu aso bade.

(b)Ti oba so aṣiṣe yoo gba esan kan, yoo siri idariji lori aṣiṣe naa.

[2]Ti idajọ ko ba han si: O gbọdọ duro ni, osi to kose afarawe ni akoko yi nitori pe kosemase ni.

Afarawe ni aaye meji:

[1] Ki alafarawe jẹ alaimọ ti komọ idajọ fun rarẹ: opi dandan fun kose afarawe nitori Olohun sope: ebéèrè lọ́wọ́ àwọn onimimo tí ẹ kò bá mọ̀

[2]ki isẹlẹ kiakia ba sẹlẹ si mujtahid, tio si raye lati woye si; ole to se ifarawe ni akoko yi.

Afarawe pinsi ona meji:

[1] Gbogbogbo:
Óhun nipé kio duni mo oju ona kan, tí ó malo ìpinnu re nibi gbogbo ọ̀ràn ẹ̀sìn rẹ̀, Awon alfa yapa enu lorie, Onbe ninu won eniti ope leewo, nitori itẹle elomiiran yatọ si Anabi wanbe.

[2]eleyan kan:
Kio mu ọrọ kan pato ninu isele kan; Eleyi to ti ko ba le mọ otitọ, boya:

[A]Okaga ra looto ni

[b]Tabi oleṣe pẹlu inira nla.

Onkowe sọpé:

Ikhin e, ope ni fun Olohun, Oluwa gbogbo eda, ike ati ige Olohun ko maa ba asiwaju wa Muhammad ati awon ara ile re ati awon saaba re titi di ojo igbende.

A n be Olohun Oba ki O san onkọwe ni esan re, ki O si ko awa ati e po sinu Aljanah, Ire Olohun olore, Ope ni fun Olohun Oba gbogbo aye, ike ati ige Olohun ko maa ba Anabi wa Muhammad.

# idanwo:

## [1] Dahun awọn ibeere wọnyi:

| | |
|---|---|
| Kilode tia ṣen keko awọn ipinle mẹfa? | ............................................................ [١]<br>............................................................ [٢] |
| Darukọ awọn ipinle mẹfa ati awọn idakeji wọn: | ............................................................ [١]<br>............................................................ [٢]<br>............................................................ [٣]<br>............................................................ [٤]<br>............................................................ [٥]<br>............................................................ [٦] |
| Darukọ iyato marun laarin awọn woli Olohun ati awọn woli Satani: | ............................................................ [١]<br>............................................................ [٢]<br>............................................................ [٣]<br>............................................................ [٤]<br>............................................................ [٥] |

## [2] Yan idahun to lalaafia

| |
|---|
| Awọn ipinle mẹfa:<br>☐ won panupo lorie. ☐<br>Iyapa enu wa lori rẹ. |
| Didarukọ nọmba ninu Quran ati Sunnah<br>Oni agboye. ☐<br>Ko ni agboye. ☐ |

| |
|---|
| Alaye wa lori e. ☐ |
| Awọn eroja itumọ ati agboye:<br>mẹta. ☐<br>mẹrin. ☐<br>marun. ☐ |

[3] Dahun pelu "otitọ" tabi "asise":

| asise | otitọ | ibeere |
|---|---|---|
| ☐ | ☐ | Won le daruko Nọmba ṣugbọn koma ni agboye; gegebi: awon ilekun Aljannah. |
| ☐ | ☐ | Won le daruko Nọmba kosi ni agboye; gegebi awom mẹ́wàá tio wo Aljannah. |
| ☐ | ☐ | Didaruko nọmba nijoko tọka si kia le ranti awon oro ni. |
| ☐ | ☐ | Maadala onkowe to ko iweyi jo pelu nomba. |

[4] Fi iyika yika nọmba toni agboye (iyen nipe ti ao le se afikun si) ninu awon oro yii:

| | | | |
|---|---|---|---|
| "Nkan marun ninu adamo" | Awọn ipinle mẹta. | Awọn ẹṣẹ meje ton pani. | Àwọn Òpó Ìgbàgbọ́. |
| Dhikr lẹhin awọn irun ọranyan. | "Awọn eniyan meji jẹ keferi ninu awọn eyan." | "Ijo mi yóò pín sí ọ̀nà mẹ́tàlélọ́gọ́rin." | Fífọ ìgbà lee meje tí ajá bá tenu bo. |

[5] Ninu awọn Tira Sheikh Muhammad omo Abdul Wahhab, Tọkasi awon nọmba ti ale ṣe afikun, ati awon nọmba ti

ao le se afikun re ninu awon oro wọnyi:

| | | | |
|---|---|---|---|
| Awọn ipinle mẹfa. | Awọn nkan mẹwa ton tu Islam. | Awọn ofin mẹrin | Awọn ipinle mẹta. |
| .............. | .............. | .............. | .............. |